# THE INTERNATIONAL DAY OF PRAYER AND AWARENESS AGAINST HUMAN TRAFFICKING



## 8 FEBRUARY

FEAST OF

**SAINT BAKHITA**

A LIGHT AGAINST

**HUMAN TRAFFICKING**

# THE INTERNATIONAL DAY OF PRAYER AND AWARENESS AGAINST HUMAN TRAFFICKING

**ÀDÚRÀ SÍ BÁKHÍTÀ MÍMỌ́**

Ẹ jẹ́ kí a gbàdúrà.
A ké pè ọ́, Jòsẹ̀fínà Bákhítà Mímọ́,
ìwọ ẹni tí a tà lẹ́rú ní ọmọ kékeré,
tí ìwọ́ sì ti rí ìpọ́njú àti ìṣòro àìlónkà.
Bí ìwọ ti rí ìdandè ara rẹ
ni ìwọ́ tùn bá ìràpadà pàdé nínú Jésù Krístì àti Ìjọ rẹ̀.
Bákhità Mímọ́, dákun wá ṣèrànlọ́wọ́ fún àwọn tí ìkẹ́kùn ìkólẹ́rú ti mú.
Jẹ́ alágbàwí fun wọn níwájú Ọlọ́run Aláàánú
kí àwọn ẹ̀wọ̀n tí a fi dè wọn fún iṣẹ́ ẹrú já kúrò.
Kí Ọlọ́run tìkaláraarẹ́ jọ̀wọ́ ṣè ìdàndè fún àwọn tó wà nínú ewu,
àwọn tó ti ń joró, tàbí ti a lò ní ìlòkílò
nítorí òwò kíkó ọmọ ènìyàn lẹ́rú yìí.
Mú ìtura wá fún àwọn tó ti bọ́ kúrò nínú iṣẹ́ ẹrú náà,
kọ́ wọn láti gbójúlé Jésù gẹ́gẹ́bí àpẹẹrẹ ìrètí àti ìgbàgbọ́
kí wọ́n bàa lè rí ìwòsàn kúrò nìnú ìrora wọn.
Àwá ń bẹ̀ ọ́ kí o gbàdúrà fún wa, kí o sì ṣìpẹ̀ fún wa
kí a má ṣe bọ́ sínú àìbìkítà
kí a lè lajú wa rí ìpọ́njú àti ìjìyà ọ̀pọ̀lọ́pọ̀ àwọn arákùnrin àti àwọn arábìnrin wa
tí a ti gba òmìnira àtì ọ̀wọ̀ ènìyàn kúrò láyé wọn,
kí a sì lè gbọ́ igbe wọn fún ìrànlọ́wọ́.

**Àmín**